**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ÌTÚSÍLẸ̀ ÌDÍLÉ (2)**
**OṢÙ KỌKÀNLÁ 2022**
Ìwé Mímọ́ kíkà: Génésísì 49
Ìjẹ́wọ́: Lúkù 4:18

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìrúnú àwọn ikán àjẹ́ lórí igi ìdílé mi, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
6. Ẹ̀yin ángẹ́lì ogun, ẹ gbá igi ìdílé mi mú, ẹ gbọn gbogbo ẹranko tó n kó àdàlù bá ni, tó n gbé lórí igi náà dànù, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí iná afọ̀mọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ jó di éérú, gbogbo ìmísí sátánì lórí igi ìdílé mi, ní orúkọ Jésù.
8. Ìwọ Gòlíátì ìrandíran, ayé mi kì í ṣe èrò rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo ẹ̀mí òkùnkùn ẹ̀jẹ̀ tó n dàmú ayé mi, di gbígbá jáde nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo gbèsè ìran, tó n yọ ayé mi lẹ́nu, jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ìjì òkùnkùn, tó n jà lòdì sí ìran mi, dópin, ní orúkọ Jésù.

**12.** Gbogbo ọ̀gbẹlẹ̀, tó n gbógun ti ewé igi ìdílé mi, gbá dánù, ní orúkọ Jésù.

**13.** Gbogbo afẹ́fẹ́ líle, tó n dojúkọ èso igi ìdílé mi, gba ìmúso, ní orúkọ Jésù.

**14.** Gbogbo ọ̀gbàrá òkùnkùn, tí wọ́n yàn ti igi ìdílé mi, gba itìjú, ní orúkọ Jésù.

**15.** Gbogbo ilé ìkẹ́rù sí òkùnkùn, tí ó há gbogbo ibùkún ìran mi mọ́, tú àwọn ibùkún wa sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.

**16.** Gbogbo obìrí ibi nínú ìran ẹ̀jẹ̀ mi, tó n yọ Ísráẹ́lì wa lẹ́nu, kú, ní orúkọ Jésù.

**17.** Gbogbo agbára tó lágbára, tó n gbógun tìmí lọ́nà àjèjì, kú lọ́nà àdìtú, ní orúkọ Jésù.

**18.** Aṣìṣe àwọn òbí mi kòní di àjálù tèmi, ní orúkọ Jésù.

**19.** Àìṣedédé ilé bàbá mi kòní jàmí lólè, ní orúkọ Jésù.

**20.** Ohunkóhun tí ọ̀tá gbékalẹ̀ lòdì sí ìran mi, gba ìfagilé, ní orúkọ Jésù.

**21.** Gbogbo májẹ̀mú ìrandíran, tó n ró ìyà àti ibànújẹ́ lágbára nínú ìran mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.

**22.** Lábẹ́ ègún ìyówù tí ìdílé mi n ṣe làálà lábẹ́ rẹ̀, fọ́ nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.

**23.** Jésù Olúwa, rìn padà lọ sínú ìpìlẹ̀ mi, ṣe àtúnkọ tí yóò mú ayé wa tẹ̀sìwájú, ní orúkọ Jésù.

**24.** Olúwa, rìn padà sí ìran mẹ́wà sẹ́yìn nínú ìran mi, k'Osì parẹ́ gbogbo òfin sátánì tí ọ̀tá n lò lòdì sí wa, ní orúkọ Jésù.

**25.** Gbogbo àkọsílẹ̀ ìkà, tí wọ́n ṣètò sínú ìpìlẹ̀ mi nípa ṣẹ̀ ibọ̀rìṣà, ẹ̀jẹ̀ Jésù, pawọ́n rẹ, ní orúkọ Jésù.

**26.** Gbogbo afẹ́fẹ́ òdì, tó n fẹ́ lòdì sí igi ìdílé mi, mo pàṣẹ́ kí o fẹsè fẹ, ní orúkọ Jésù.

**27.** Gbogbo gbólóhùn sátánì lórí ayé mi láti ìgbà ọmọdé wá, kú nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.

**28.** Iná Ọlọ́run, wẹ igi ìdílé mi mọ́, kosì sọwá di pípé, ní orúkọ Jésù.

**29.** Mo gba gbogbo ibùkún ìrandíran tó somọ́ ìran mi, ní orúkọ Jésù.

**30.** Ìlànà ibi tàbí ìdè ìyówù, tó tún n farahàn lémọ-lémọ lórí igi ìdílé mi, gbọ̀n dànù nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ Jésù, ní orúkọ Jésù.

**31.** Gbogbo májẹ̀mú ìpìlẹ̀ tó n ṣàn nínú ìran mi, di asán, ní orúkọ Jésù.

**32.** Ẹnu ọ̀nà ìgbà láíláí àti ọkùnrin alágbára, tí wọ́n yàn láti yọ Ísráẹ́lì ìran mi lẹ́nu, dí gbígbá dànù nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.

**33.** Àwọn ìwà búburú sátánì, tó n pọ́n ìtẹ̀síwájú ìdílé mi lójú, gba ìmúso nípa agbára Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.

**34.** Gbogbo àyalù àwọn ọmọ àjèjì sínú igi ìdílé mi, gba ìmúso nípa agbára Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.

**35.** Gbogbo ètò òkùnkùn, tó n tako títóbi ìdílé mi, ká dánù, ní orúkọ Jésù.

**36.** Àwọn oníṣẹ́ abẹ tó n ṣàbójútó igi láti ọ̀run, ẹ bẹ igi ìdílé mi wò, kí ẹ sì jẹ́ kí ìtúsílẹ̀ nlánlà ṣẹlẹ̀, ní orúkọ Jésù.

**37.** Ìdílé mi, rìn jáde kúrò nínú ihò kinìún òṣì àti ìpadàṣẹ́yìn, ní orúkọ Jésù.

**38.** Gbogbo kòkòrò jewéjewé àti irú kòkòrò kejì, tí wọ́n yàn láti yọ igi ìdílé mi lẹ́nu, rún wómúwómú, ní orúkọ Jésù.

**39.** Gbogbo ìlànà panṣágà, ìkóbìnrin jọ, àṣejù nínú ìbálópọ̀, àwọn ìwà ipá, dídi bárakú fún nkan àti ikú, gba ìfagilé, ní orúkọ Jésù.

**40.** Agbára àjínde, jí ayànmọ́ mi dìde kúrò nínú pósí, ní orúkọ Jésù.